## ẸKỌ 442 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Gbogbo awọn wọnyi li o kú ni igbagbọ́, lai ri ileri wọnni gbà, ṣugbọn ti nwọn ri wọn li òkere rere, ti nwọn si gbá wọn mú, ti nwọn si jẹwọ pe alejò ati atipò li awọn lori ilẹ aiye" (Heberu 11:13).**

### A Sọ itumọ Igbagbọ́

**"Njẹ igbagbọ́ ni idaniloju ohun ti a nreti, ijẹri ohun ti a kò ri" (Heberu 11:1).**

Lẹyin ti Paulu ti fi hàn gẹgẹ bi awọn Ju ti kuna patapata nitori aigbagbọ́ wọn, o bẹrẹ ọrọ rẹ lori ori kọkanla iwe Heberu yii lati fi hàn pe ipilẹ iwa-bi-Ọlọrun ni igbagbọ́ -- igbagbọ́ ninu ọkàn. Igbagbọ́ ni oore-ọfẹ ninu ọkàn ti n mu ki eniyan le ri ohun airi. Ohun ti o wà ninu ọkàn Paulu ni yii nigba ti o wi pe:

**"Niwọn bi a kò ti wò ohun ti a nri, bikoṣe ohun ti a kò ri: nitori ohun ti a nri ni ti igba isisiyi; ṣugbọn ohun ti a kò ri ni ti aiyeraiye" (2 Kọrinti 4:18).**

Igbagbọ́ nikan ṣoṣo ni o lè mu ki eniyan ri ohun airi, a maa mu ki a ri ohun airi, a si maa sọ ohun ti a kò mọ̀. Ohun ti igbagbọ́ n ṣe tayọ pe ki o kàn jẹ ki a le gbagbọ; a maa mu ki a ni imọ̀. Eyi ni idi rẹ̀ ti Paulu fi pe e ni ifihan ohun ti a kò ri. Yoo mu ki o hàn gbangba fun oju lati ri i, a si fi i sinu ọkàn ni ọna ti o daju to bẹẹ ti ki yoo si tabitabi kan mọ́. Lọna bayii ni idaniloju fi n wọ ọkàn Onigbagbọ́; nipa igbagbọ́ o ni ipilẹ ti o le fi gbogbo ọkàn sinmi lé. Ohun ti Isaiah n tọka si ni eyi nigba ti o n sọ nipa ipilẹ ti o daju. Ipilẹ naa ni Kristi; igba ti a ba si fi idi wa kalẹ lori Rẹ̀, idaniloju kan yoo wọ inu ọkàn wa lọ eyi ti ohunkohun kò le lé jade. Lati inu ipilẹ igbagbọ́ yii ninu ọkàn ni gbogbo iwa rere igbesi-ayé Onigbagbọ́ yoo ti maa ṣàn jade.

Eyi ni ohun ti o fun awọn baba ninu igbagbọ́, awọn eniyan Ọlọrun, ati awọn ajẹriku igbaani ni agbara ati foriti orişirişi işoro, lati duro loju atako ayé ati ifişẹsin awọn eniyan, ati awọn oninunibini ti n lepa wọn kiri bi ekute, sibẹ ti wọn di igbagbọ́ wọn mú -- wọn ni idaniloju ninu ọkàn wọn. Ipilẹ wọn duro lori awọn ohun ti a kò fi oju ri. Paulu tẹ̀ siwaju lati maa darukọ lẹsẹẹsẹ awọn ọkunrin ati obinrin ti wọn ti gbé nigba Majẹmu Laelae, awọn ti a ti n kọ́ ẹkọ nipa wọn, o si fi hàn bi ẹni kọọkan wọn ṣe bori, bi wọn ti sure ije wọn, bi wọn si ti ṣe pari ire-ije wọn, ti wọn si ṣẹgun nipa igbagbọ. O bẹrẹ lati atetekọṣe, ṣugbọn a kò darukọ Adamu – a le e jade kuro ninu Ọgbà. O ni anfaani nla ti rẹ̀, ṣugbọn o sọ ọ nù nitori ohun ti kò tilẹ ni laaari to ipẹtẹ; nitori naa a kò darukọ rẹ̀ mọ́ awọn eniyan nla. Awọn eniyan wọnyii, ti ailera yika niha gbogbo, ti wọn kò si gbadun iru anfaani ti Adamu ni, bori nibi ti Adamu ti kunà.

### Abẹli ati Kaini

Adamu fi oju ara rẹ̀ ri i laaarin ile rẹ̀ ohun ti ẹ̀ṣẹ n ṣe, ohun ti aigbọran ninu Ọgbà le mu wá gẹgẹ bi ikore; eyi si bẹrẹ lori awọn ọmọ rẹ̀. A o bẹ̀rẹ̀ lati ọdọ Abẹli.

**"Nipa igbagbọ́ ni Abẹli ru ẹbọ si Ọlọrun ti o san ju ti Kaini lọ, nipa eyiti a jẹri rẹ̀ pe olododo ni, Ọlọrun si njẹri ẹ̀bun rẹ̀: ati nipa rẹ̀ na, bi o ti kú ni, on nfọhùn sibẹ̀" (Heberu 11:4).**

A le pada sinu akọsilẹ nipa Abẹli ninu Gẹnẹsisi 4:3-15. Awọn ọkunrin wọnyii mu ẹbọ wa nigba atekekọṣe yii. Eyi paapaa fi hàn pe wọn mọ pe o jẹ́ ọranyan fun wọn lati bá Ọlọrun laja. Ohunkohun iyowu ki imọ wọn le jẹ nipa otitọ, wọn mọ pe awọn wà ni iyapa si Ọlọrun; wọn si ni lati ṣe ohun kan lati mu wọn pada bọ̀ si iṣọkan pẹlu Ọlọrun. Iru ọkàn bayii ni a maa n ri laaarin gbogbo iran ẹda ohunkohun iyowu ki ẹsin wọn le jẹ́. Awọn Keferi paapaa a maa ṣe irubọ si awọn ọlọrun wọn. Irubọ ti wọn n ṣe yii tọka si i pe wọn gbà pe ẹ̀ṣẹ wà ninu ayé wọn. Ẹmi Ọlọrun ti n dá ni lẹbi fun ẹ̀ṣẹ ni o n ṣe eyi ninu wọn.

Otitọ ti wọ inu ọkàn Abẹli. Boya o ti wọ inu ọkàn Kaini paapaa, ṣugbọn ọkàn ti o fi gba a yatọ patapata. Mo gbagbọ pe Kaini naa mọ̀ ohun ti o tọ́ lati ṣe lati mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ gẹgẹ bi Abẹli ti ṣe, ṣugbọn o kọ̀ lati ṣe e. Iru ẹmi ti awọn eniyan n fi hàn lode oni ni o fi hàn – eekun ti ki yoo tẹba, ifẹ inu ẹni ti ko le tuuba, iwa ti n ṣe lodi si Ọlọrun.

Abẹli fi ọdọ-agutan rubọ, o gbe e le ori pẹpẹ, Oluwa si tẹwọ gba a – boya nipa fifi iná dahun lati Ọrun – nigba ti a kọ ti Kaini silẹ. Nigba naa ni inu bi Kaini. O dide si arakunrin rẹ̀ o si pa a, lẹyin ti Oluwa tilẹ ti kilọ fun un.

Abẹli mu ẹbọ ti o ni ẹ̀jẹ wá, ọdọ-agutan ti a pa, lai si eyi ti ko si imukuro ẹ̀ṣẹ. Nipa bayii o wá idalare nipa igbagbọ́. Kaini, ni idakeji, ni titẹle ohun ti ọkàn ẹ̀ṣẹ n wí, mu eso ilẹ wá, èrè iṣẹ́ ti o ṣe, nipa bayii o n wá idalare nipa iṣẹ́. Idi rẹ̀ ni eyi ti a fi gba ẹbọ Abẹli ṣugbọn ti a kọ ti Kaini. Lati igba atetekọṣe yii ni a ri ifarahan oriṣi ẹsin meji ti o wà: ẹsin tootọ ti o ti ọdọ Ọlọrun wá ti o n beere Ẹjẹ Etutu fun ẹ̀ṣẹ; ti o si n fun ni ni idalare nipa igbagbọ́; ati ẹsin eke ti a fi ipasẹ eniyan gbé kalẹ̀, ẹsin ti ko ni ẹ̀jẹ ninu iru eyi ti o n wá idalare nipa iṣẹ́. Eyi gan an ni kókó pataki ti o wà ninu Ẹsin-igbalode ti ode-oni: wọn ni ki i ṣe ọranyan lati ni irubọ. Ẹjẹ Etutu ni gan an ni koko pataki ti awọn ẹlẹsin igbalode n tako. Wọn ṣetan lati gba Jesu gẹgẹ bi olukọni; wọn ṣetan lati gbà pe ọga kan ni; wọn n fẹ lati tọka si I gẹgẹ bi apẹẹrẹ nlá nlà: ṣugbọn nigba ti o ba de ibi koko pe O fi ẹmi Rẹ̀ lelẹ ni ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ, wọn kọ̀ lati gba eyi. Awọn ẹsin meji yii ni o ti wà titi di igba ayé isisiyi.

**Enọku**

> **"Nipa igbagbọ́ li a ṣí Enọku nipò pada ki o máṣe ri ikú; a kò si ri i, nitoriti Ọlọrun ṣí i nipò pada: nitori ṣaju iṣipopada rẹ̀, a jẹri yi si i pe o wù Ọlọrun.**
>
> **"Ṣugbọn li aisi igbagbọ́ kò ṣe iṣe lati wù u; nitori ẹniti o ba ntọ̀ Ọlọrun wá kò le ṣai gbagbọ́ pe o mbẹ, ati pe on ni olusẹsan fun awọn ti o fi ara balẹ wá a"**

Diẹ kinun ni a mọ̀ nipa itan igbesi-ayé Enoku, ṣugbọn diẹ ti a fun wa sọ pupọ. Ni ọna kin-in-ni o wi bayii pe Enọku bá Ọlọrun rìn. A mọ̀ nipa bayii pe o jẹ́ ẹni mimọ́ ati olododo. Oun pẹlu, bi Abẹli ti ṣe ohun ti Ọlọrun n beere o si ti mu ẹbọ wá eyi ti o ṣe itẹwọgba fun Oluwa, o si ti gba iwa-mimọ́ yii nipa ṣiṣe bẹẹ.

Adamu bá Ọlọrun rin ṣaaju iṣubu rẹ̀, bẹẹ ni pipe iwa mimọ́ ati ododo ni a dá a. Kò si ẹni ti o le bá Oluwa rin lai si awọn oore-ọfẹ wọnyii. O gba pe ki a kún fun otitọ ati ki a rin ni mimọ́ iwà lati le bá Ọlọrun wà ni irẹpọ; kò si ọna miiran ti ẹnikẹni le gbà bá Ọlọrun wà ni irẹpọ. Ọrọ ti a pè ni "rin" ni itumọ ti o jinlẹ. Itumọ kan ti a fun un ni ede Heberu ni pe: Enoku fi ara rẹ̀ si ipò lati bá Ọlọrun rin. Eyi n fi ipinnu hàn. Kò bá Ọlọrun rin gẹgẹ bi igba ti eniyan n ṣe faaji nitori o jẹ́ irọrun fun un, ṣugbọn o lọ́ ara rẹ̀ si ṣiṣe bẹẹ, o pinnu lati ṣe e.

Fiyesi awọn iwa rere ọkunrin yi: iwa mimọ, ododo, ipinnu. O bá Ọlọrun rin fun ọọdunrun (300) ọdun. A ko ri ninu akọsilẹ pe o fa sẹyin ni gbogbo akoko yii. Eyi n fi iforiti hàn. Lẹyin eyi ọrọ naa wi pe o wu Ọlọrun. Itumọ eyi, ni ọna kan, ni igbọran. Kò ṣanfaani fun eniyan lati maa sọrọ nipa igbagbọ́ ti oun ni ninu Ọlọrun ki o si ṣe aigbọran si i. Awọn ẹmi eṣu bẹru wọn si wariri. Bi eniyan ba ni igbagbọ́ gẹgẹ bi Ọrọ Bibeli, a maa gbọran si Ọlọrun a si maa rin ninu ofin ati ilana Rẹ̀.

Itumọ gbogbo nnkan wọnyii ni pe Enọku ni ọkan pipé, ọkàn ti o wà ni ipo lati maa wu Ọlọrun ninu ohun gbogbo ti o n ṣe. Nipa igbagbọ ni Enọku bá Ọlọrun rin. Lai ṣe aniani, Ẹni airi ni Ọlọrun gẹgẹ bi o ti jẹ́ ẹni airi fun Mose; ṣugbọn Mose duro ṣinṣin gẹgẹ bi ẹni ti o n ri Ẹni Airi. Lai si aniani Enọku rin bẹẹ gẹgẹ. Bi a o ba ri Ọlọrun a o ri I nipa igbagbọ. Ki i ṣe pẹlu oju ti ara yii, ṣugbọn nipa oju igbagbọ́. Lai si aniani, eyi ni o mu ki Enọku duro ṣinṣin. Ohun kan naa ni o mu ki Mose duro ṣinṣin. Nipasẹ igbagbọ kan naa yii ni a ṣi Enọku nipo pada. Itumọ eyi ni iyipada lọgan – ni iṣẹju aya, ni iṣẹju kan. Enọku ni iriri iyipada yii lai lọ sinu iboji. O n ba Ọlọrun rin ninu idapọ ati irẹpọ pẹlu Rẹ̀ titi akoko kan de ti ẹsẹ rẹ̀ ṣi kuro ninu ayé yii ti o si lọ kuro, ti awọn ọrẹ rẹ̀ ko ri i mọ́. Ọrọ̀ Ọlọrun ti a kọ nipa imisi sọ fun wa pe a pa a lara dà. Eyi si ṣẹlẹ ṣaaju igba ikun-omi.

Enọku gbé ninu ayé ni igba atetekọṣe nigba ti o ṣe e ṣe ki o má si ilà kan ninu Ọrọ Ọlọrun ni akọsilẹ, sibẹ o bá Oluwa rìn timọtimọ, o si dé oju odiwọn ti Ọlọrun n beere to bẹẹ ti ọwọ́ rẹ̀ fi tẹ anfaani ti a pe Ijọ Kristi si: lati wà ni imurasilẹ de ọjọ ni ti Oluwa yoo fara hàn. Iṣipopada Enọku jẹ́ apẹẹrẹ ipalarada Ijọ. A tun ri apẹẹrẹ miiran lẹyin eyi ni ti Elijah, ni akoko awọn wolii.

**Noa**

**“Nipa igbagbọ́ ni Noa, nigbati Ọlọrun kilọ ohun ti a koi ti iri fun u, o bẹru Ọlọrun, o si kàn ọkọ̀ fun igbala ile rẹ̀, nipa eyiti o dá aiye lẹbi, o si di ajogún ododo ti iṣe nipa igbagbọ́.**

Akoko ti Noa gbé ninu ayé ki i ṣe akoko ti o wú ni lori pupọ. A ni apejuwe kikún nipa iru ipo ti ayé wà ni igba ti rẹ̀. Apejuwe naa fi hàn pe iwa buburu eniyan pọ̀, ayé si kun fun iwa ipá, a si sọ ilẹ di ibajẹ labẹ awọn olugbe ori rẹ̀.

Ayé kò ti i di arugbo pupọ nigba ayé Noa ṣugbọn Ọlọrun ṣetan lati mu un wá si opin. A maa ya awọn eniyan lẹnu nigba miiran pe ki ni idi rẹ̀ ti Ọlọrun fi gba awọn nnkan ti o wà ninu ayé laye bẹẹ. Oun yoo mu un wá si opin ni akoko ti Rẹ̀.

Ọlọrun ri gbogbo nnkan ti o n ṣẹlẹ ni akoko Noa. Nnkan miiran ti O sọ ni pe ẹran ara ni eniyan; eyi yii ni pe o ti jọwọ ara rẹ̀ patapata fun ara. Wiwà fun ara ati wiwà fun ohun ti ara jẹ ohun ti o gbilẹ ni akoko ti rẹ̀. Ṣugbọn laaarin iru ipo yii ni a ri Noa, ẹni kan ti iwa rẹ̀ tayọ.

Ọrọ naa wi nipa rẹ̀ pe o jẹ “olododo.” Eyi ni pe o jẹ olotitọ, pe o ti ni iriri idalare tootọ, boya o tilẹ ni isọdimimọ́ pẹlu. O bá Ọlọrun rin bi ti Enọku: “o fi ara rẹ̀ sipo lati ba Ọlọrun rin.” O tun sọ nipa rẹ̀ pe oun jẹ́ pipe ninu gbogbo iran ti rẹ̀. Nibẹ a ri ohun mẹta ti a sọ nipa Noa eyi ti o yatọ patapata si ohun ti a sọ nipa ayé: o jẹ́ olododo, o bá Ọlọrun rin, o si jẹ́ ẹni pipé ni iran ti rẹ̀.

Ohun iyanu ni fun wa lati ri ipo giga nipa ti ẹmi ti awọn baba nla ninu igbagbọ́ ti igba laelae dé pẹlu imọlẹ diẹ ti wọn ni. O ba ni ninu jẹ lati ṣe akiyesi pe isin lẹmi ati lotitọ kere lọjọ ni ayé wa isisiyii pẹlu gbogbo ọlaju ati odiwọn igbagbọ ninu eyi ti a ni anfaani gbogbọ Ọrọ Ọlọrun lọdọ wa. Idi rẹ̀ ni yii ti ori iwe yii fi jẹ iṣiiri pupọ fun Onigbagbọ́.

Ni akoko Noa Ọlọrun pinnu lati pa gbogbo ohun alaaye run; sibẹ O fun wọn ni anfaani ọgọfa ọdun ninu eyi ti wọn le ronupiwada ki wọn si wá Ọlọrun bi wọn ba yàn lati ṣe bẹẹ. Ṣugbọn ni gbogbo ọdun wọnyii a kò gbọ́ pe ẹni kan ṣoṣo ninu wọn mu anfaani yii lò tabi ki wọn ṣe ohunkohun lati wá Ọlọrun.

Nikẹyin akoko naa de ti Noa wọ inu ọkọ̀. Ohun gbogbo ti pari, iṣẹ ti o kù ni a ti pari rẹ̀, oun ati awọn ẹranko ti yoo mu ki ohun alaaye kù lori ilẹ ayé si wọ inu ọkọ̀. A sọ fun ni pe Ọlọrun sé wọn mọ́ inu ọkọ̀. Ilẹkun kan naa ti o sé wọn mọ́ inu ọkọ ni o sé awọn iyoku mọ́ ita. Eyi n sọ pe iparun de bá ayé.

Gẹgẹ bi a ti sé ilẹkun ni, bakan naa ni ilẹkun oore ọfẹ yoo ti lọjọ kan eyi yoo jẹ́ idajọ lori awọn ẹlẹṣẹ ayé isisiyii. Ohun ti o mu ki eyi ye wa yekeyeke ni ohun ti Jesu sọ nipa akoko yii:

**“Gẹgẹ bi ọjọ Noa si ti ri, bẽni wíwa Ọmọ-enia yio si ri” (Matteu 24:37).**

Ṣe akiyesi gẹgẹ bi ayé wa isisiyii ti fara jọ igba ayé Noa pọ̀ tó: ayé kún fun iwa agbara, iwa buburu eniyan di pupọ ninu ayé, ayé si bajẹ labẹ awọn olugbe inu rẹ̀. Eyi jẹ́ akawe kikún nipa awọn nnkan ti o n ṣẹlẹ ninu ayé isisiyii. Awọn nnkan wọnyii mu ki a mọ̀ pe akoko wa yii sun mọ igba bibọ̀ Ọmọ Ọlọrun pẹkipẹki.

Gbogbo ohun ti Noa ṣe, nipa igbagbọ́ ni o ṣe e. A sọ fun wa pe “o bẹru.” Eyi ki i ṣe ibẹru iparun ti rẹ̀ tabi ti awọn ara ile rẹ̀; eyi jẹ ibẹru ti o kún fun itẹriba fun Ọlọrun -- ibẹru pe ki oun má ba ṣiyemeji Ọrọ Ọlọrun ni iṣẹju kan. O gba Ọlọrun gbọ́ gẹgẹ bi O ti wi gan an, o si bẹrẹ iṣẹ ni i ṣe nipa kikan ọkọ naa, nigba ti ko tilẹ si ami kan nipa ikun omi. Boya eyi jọ iwa aṣiwere ni ọkàn awọn ti o kù ni aye igba naa: ṣugbọn o ṣẹ gẹgẹ bi Oluwa ti wi.

**Abrahamu**

**“Nipa igbagbọ́ ni Abrahamu, nigbati a ti pè e lati jade lọ si ibi ti on yio gbà fun ilẹ-ini, o gbọ́, o si jade lọ, lai mọ̀ ibiti on nrè” (Heberu 11:8).**

Awọn eniyan Ọlọrun wọnyii fara hàn lati akoko de akoko gẹgẹ bi iná nla ti n tàn lori oke. A ri Noa ni akoko ti rẹ̀; ni nnkan bi irinwo ọdun lẹyin eyi Abrahamu ni o tun kàn ni akoko ti rẹ̀; ati bẹẹ bẹẹ lọ. Wọn duro gẹgẹ bi ẹri oore-ọfẹ Ọlọrun ti o n gba ni là -- ẹri ohun ti igbagbọ́ le ṣe ninu ọkàn ọmọ eniyan.

Ohun iyanu ni pe Abrahamu ko jiyan ipe naa, ko tilẹ sọ ọrọ kan. Lẹsẹkẹsẹ ni o bẹrẹ si mura silẹ; ẹni kan ṣoṣo ninu awọn eniyan rẹ ti o ni ifẹ lati ba a wá ni Lọti. Bẹẹ ni Abrahamu mu iyawo rẹ ati awọn ti o wà pẹlu rẹ (awọn iranṣẹ rẹ lai si aniani), wọn mu ọna ajo wọn pòn lati lọ si ilẹ naa ti wọn ko mọ ohunkohun nipa rẹ. Ọrọ Ọlọrun wi pe, "Ni ilẹ Kenaani ni nwọn si wá si" (Gẹnẹsisi 12:5). Ọrọ wọnni dùn mọ́ ọkàn mi pupọ. O dún (ni eti eniyan) bi ẹni pe Abrahamu mura iṣẹ gidi. O ṣe gbogbo rẹ nipa igbagbọ́.

Niha gbogbo ni ibọriṣa yí Abrahamu ká. Ko si ohunkohun ni ayika rẹ ti o le tọka rẹ si Ọlọrun alaaye; Oluwa si ni lati wu u ti-gbongbo-gbongbo, ki a ba le tun un gbin. Ọlọrun beere ipinnu ti o mura tán patapata lati jade lọwọ Abrahamu.

Ọlọrun a maa ṣe iṣẹ rẹ ni aṣepe nigba gbogbo. Awọn ẹlomiran a maa sun ẹsun pe Ihinrere le hú nnkan tigbòngbò-tigbòngbò. Ọrọ iyin ni eyi jẹ́ fun Ihinrere nitori Ihinrere ti n kó akoja ohun gbogbo ni. Nigba ti Ọlọrun ba bẹrẹ si ṣiṣẹ Rẹ̀, ohun gbogbo ni i maa lọ bi Oun ti pinnu rẹ̀, Oun si n fẹ igbọran pipe si Ọrọ Rẹ̀. Ohun ti o jọ ni loju pupọ nipa awọn eniyan Ọlọrun wọnyii ni pe, bi Ọlọrun ba ti n sọrọ wọn a si dide lọgan lati ṣe e, bi o tilẹ ṣe pe yoo gbà wọn ni ẹmi wọn. Ohun ti iṣẹ isin wọn si Ọlọrun jẹ́ ni eyi. Ohunkohun ti o wù ki o gbà wọn, wọn ko jẹ duro, bi o ti wu ki ifi-ara-rubọ naa ti le tó.

Mo n fi oju inu wo o bi Abrahamu ti n já ara rẹ̀ kuro lara ohun gbogbo ti o yi i ká, kuro lara awọn ẹlẹgbẹ rẹ̀, kuro lara ohun wọnni ti o so ó pọ̀ mọ ẹbi rẹ̀; ti o si n jade lọ pẹlu awọn eniyan diẹ ti o n ba a bọ̀ si ilẹ ti wọn ko mọ̀ ri. O gba a ni ohun kan lati ṣe, ṣugbọn o ṣe bẹẹ nigba ti Ọlọrun pe e. O dé ilẹ ti ko mọ ri yii. A ri i bi o ti n lọ si iha ila oorun Bẹtẹli. Nibẹ ni o pa agọ rẹ̀ o si tẹ́ pẹpẹ kan fun Oluwa.

Ohun kin-in-ni ti Abrahamu ṣe ni lati tẹ́ pẹpẹ kan. Iwọ yoo kiyesi bi o ti n fi ọkàn bá Abrahamu lọ ninu gbogbo iṣisẹ rẹ̀ pe Ọlọrun ni akọkọ ninu gbogbo iṣe rẹ̀ nigba gbogbo. Iṣisẹkiṣisẹ ti o le wu ki o gbé, ibikibi ti o ba lọ, iwọ yoo ri i bi o ti n tẹ́ pẹpẹ fun Oluwa. Itumọ eyi ni pe o n fi idi isin kalẹ pẹlu Ọlọrun nibikibi ti pẹpẹ yii ba gbé fara hàn.

Ẹni kan n sọ nipa eyi pe "Wo o bi iye awọn eniyan ti n ronu lati kọ́ pẹpẹ fun Oluwa nigba ti wọn ba n kọ́ ile wọn ti kere to!" O si pari ọrọ rẹ̀ bayii, " Wò ó bi iye awọn olusin tootọ ti n sin Ọlọrun alaaye ti o le yọọda ohun gbogbo nitori isin Ọlọrun ti kere tó."

**"Nipa igbagbọ́ li o ṣe atipo ni ilẹ ileri, bi ẹnipe ni ilẹ̀ àjeji, o ngbé inu agọ́, pẹlu Isaaki ati Jakọbu, awọn ajogún ileri kanna pẹlu rẹ̀ (Heberu 11:9).**

Oluwa ti ṣeleri pe ilẹ yii yoo jẹ ti rẹ̀ ṣugbọn jalẹ gbogbo igba ayé Abrahamu iwọn eyi ti o tẹ ẹ lọwọ ninu ilẹ yii ni ilẹ isinku kan, owo rẹ̀ ni o si fi ra eyi ni paapaa. Lọna bayii oun tikara rẹ̀ ko fi oju rẹ̀ ri imuṣẹ ileri wọnyii, ṣugbọn ni gbogbo igba yii kò ka ara rẹ̀ si ohunkohun ju alejo ati ero. Eyi ti di ọrọ ti o wọpọ ni ẹnu awọn Onigbagbọ́ ọmọ-ẹyin Oluwa; ṣugbọn ọpọlọpọ eniyan ni o n lo ọ̀rọ yii ti iwa wọn n fi hàn paapaa ju ọrọ ẹnu wọn pe wọn ni itẹlọrun lati wà ninu ayé yii jù lati wà pẹlu Oluwa lọ. O gba ipinnu lati jẹ ero ati alejo ninu ayé yii.

Bi o ti jẹ pe iru ọmọ Abrahamu ni a o fi ilẹ yii fun – Abrahamu si ti le fi oju si ara ilẹ naa -- sibẹ Paulu sọ fun wa ohun ti i ṣe ilepa tootọ ti o wà ninu ọkàn rẹ̀.

**"Nitoriti o nreti ilu ti o ni ipilẹ̀; eyiti Ọlọrun tẹ̀do ti o si kọ́."**

Jẹ ki n bi ọ leere; Njẹ ifojusọna Abrahamu niwọn ẹẹdẹgbaa ọdun ṣaaju ibi Kristi (1900 B.C.) ha yatọ si iru ifojusọna ti Ọlọrun n fẹ fun igba isisiyii? Tabi iru ifojusọna ti o yẹ fun Onigbagbọ̀ lati ni? O jẹ ẹni ti o gbé igbesi-ayé ti o ṣe deedee pẹlu odiwọn ti akoko awọn Onigbagbọ igba oore-ọfẹ yii, ani imọlẹ ti o gbooro ti a ni lonii ninu Ọrọ Ọlọrun ni akoko Abrahamu. Gẹgẹ bi a ti mọ̀, a kò i ti i kọ ilà kan ṣoṣo silẹ ninu Ọrọ Ọlọrun ni akoko Abrahamu. Ohunkohun ti o ba gbọ́, Oluwa sọ fun un gẹgẹ bi aṣẹ tabi ọ̀rọ ni. Oju rẹ̀ ko si lara ohun ini wọnni. O mọ̀ nigba naa gẹgẹ bi awa naa ti mọ lode oni, pe ilẹ ni jẹ apẹẹrẹ Ilu Ọlọrun ti o Dara ju ayé yii lọ.

Ni tootọ ni a ṣe ileri ohun ini ayé yii fun iru-ọmọ Abrahamu, ati ibukun ti wọn yoo ni ni ilẹ yii. Bẹẹ ni iwọnyi si jẹ ti wọn nigba ti wọn gbọran si aṣẹ Ọlọrun, nitori ki Ọlọrun ba le mu eto irapada Rẹ̀ ṣẹ, ati ipinnu Rẹ̀ pe Israẹli ni yoo jẹ ohun-elo nipasẹ eyi ti a o sọ eto yii di mimọ̀ fun ayé, o ṣe pataki pe a ni lati fi idi wọn kalẹ gẹgẹ bi orilẹ-ede. Nitori naa O bukun fun wọn nipa ti ara; ṣugbọn ki i ṣe ero ọkàn

Rẹ̀ pe ki ibukun ti O fun awọn Ọmọ Israẹli ki o jẹ kiki Ilẹ Ileri gẹgẹ bi ko ti fẹ ki awọn ohun ini nipa ti ara ti O n fi fun wa lonii jẹ́ opin ohun gbogbo. O n fẹ ki a woke rekọja gbogbo nnkan wọnyii gẹgẹ bi O ti n fẹ ki awọn Ọmọ Israẹli ṣe wò rekọja ohun ini ti wọn ri gbà.

Awọn eniyan nipa ti ẹmi, awọn ti n ba Ọlọrun rin ti wọn si n ba Ọlọrun sọrọ, awọn ti wọn fẹran ohun ti ẹmi a maa riran rekọja awọn ibukun ti ara. A ko fẹ lati ni aṣiro ninu ọkàn wa nipa ohun ti ipinnu Ọlọrun jẹ́ fun awọn Ọmọ Israẹli, ki a si ro pe ibukun nipa ti ara nikan ṣoṣo ni, ati pe iwọnyi nikan ni ibukun ti a ṣeto fun wọn, nigba ti o ṣe pe fun awa ti o wà ni akoko yii a ni lati gba ibukun nipa ti ẹmi. Awọn pẹlu le ri awọn ibukun ti ẹmi gbà gẹgẹ bi awa pẹlu lode oni – bi o tilẹ jẹ pe imọlẹ diẹ ati ifihan diẹ ni wọn ni: sibẹsibẹ ibukun naa jẹ́ ti wọn. Nihin ni a ri akọsilẹ awọn eniyan ti o gbá anfaani yii mu ti wọn si ri awọn ibukun naa. Bi awọn eniyan wọnyii ba le ri wọn gbà, gbogbo Israẹli pẹlu ni i ba le ri wọn gbà.

**"Gbogbo awọn wọnyi li o kú ni igbagbọ́, lai ri ileri wọnni gbà, ṣugbọn ti nwọn ri wọn li òkere rere, ti nwọn si gbá wọn mú, ti nwọn si jẹwọ pe alejò ati atipó li awọn lori ilẹ aiye" (Heberu 11:13).**

Ohun kan n sọ ti ọrun ninu awọn ọ̀rọ wọnni. Wọn ko ri awọn ileri ti Ọlọrun ṣe gbà ṣugbọn wọn ri wọn ni okeere réré. Jesu wi pe, "Abrahamu baba nyin yọ̀ lati ri ọjọ mi" (Johannu 8:56). O ri Messiah ti n bọ̀ wa, o ri iru-Ọmọ ti Ọlọrun ti ṣeleri; eyi ni o rú ẹmi rẹ̀ soke ti o si mu ki o yọ̀.

Awọn eniyan mimọ́ ni igba ayé Paulu gba ileri bibọ̀ Oluwa lẹẹkeji gbọ́. Wọn ko ri i ni ọna jijin rere bi Abrahamu ti ri ileri wọnni; wọn ri i pe o sun mọ tosi. Ṣugbọn a ko mu un ṣe ni akoko ti wọn. Ki ni ère didi awọn ileri wọnyii mú ati yiyọ̀ ninu ireti wọn? Eyi mu ki wọn rin pẹlu iṣọra, o mu wọn gbé igbesi-ayé ti ẹmi, o si mu wọn bá Oluwa rin timọtimọ. Iru ero bẹẹ yoo mu ère kan naa wá fun wa lode oni. O ṣe ohun kan naa fun Abrahamu nigba ti rẹ̀. Bi wọn ba ti pa awọn ileri wọnni tì si apa kan ọwọ wọn ki bá ti le tẹ̀ wọn.

**"Nitoripe awọn ti o nsọ irú ohun bẹ̃, fihan gbangba pe, nwọn nṣe afẹri ilu kan ti iṣe tiwọn" (Heberu 11:14).**

Eleyi tun n tọka si Abrahamu pe o n reti "ilu ti o ni ipilẹ̀; eyiti Ọlọrun tẹ̀do ti o si kọ́," o si ka ara rẹ̀ ati ẹbi rẹ̀ si alejò ati atipó.

**"Ati nitõtọ, ibaṣepe nwọn fi ilu ti nwọn ti jade wa si ọkàn, nwọn iba ti ri aye lati pada" (Heberu 11:15).**

Bi Abrahamu ba n fẹ lati pada lọ sọdọ awọn ara rẹ̀ ati si ilu rẹ̀ Ọlọrun i ba fun un laye lati lọ. Bi o tilẹ jẹ pe Ọlọrun ṣe ileri, àfo ṣi silẹ fun Abrahamu lati yí pada nigbakigba. Ni tootọ o fẹrẹ má i ti de ilẹ nla ti o n ṣàn fun wara ati fun oyin yii tan ti iyàn fi de ba a, o si ni lati fi Kenaani silẹ titi iyàn naa fi rekọja. O ni anfaani pupọ lati jiyàn ileri Ọlọrun, ṣugbọn kò ṣe bẹẹ.

Igbagbọ mu un la gbogbo ohun wọnni ti n mu ni rẹwẹsi ati ibi iṣoro já: igbagbọ́ ninu Ọlọrun, ki i ṣe ohun miiran. Nigba ti ko le ri ohunkohun, o gbagbọ́ sibẹ o si duro. Bi ohunkohun ba wà ti o le sọ iwọ ati emi di alagbara lati bori ohunkohun ti n mu ni rẹwẹsi ati lati bori ọfa ina ẹni ibi ní, apata igbagbọ́ ni (n kò gbagbọ pe ohun kan wà ti o muna ti o le pa ni lara, ti o si le lọ jinlẹ ju imuni-rẹwẹsi lọ). Abajọ ti Paulu fi wi pe "Léke gbogbo rẹ̀, ẹ mu apata igbagbọ́' (Efesu 6:16).

Ko i ti si ohun nla kan ti o ṣẹlẹ lati di alaafia wa lọwọ lati igba ti Ọlọrun ti tú Ẹmi Rẹ̀ jade ni 1906. Agbo awọn Onigbagbọ wọnyii ti gberu; Ọlọrun ti bukun un; o si ti ṣe rere. Ni tootọ iyiriwo ti wà loju ọna, ṣugbọn iyiriwo ti o n de ba ẹni kọọkan ni o pọ ju. Ko i ti si inunibini ti a le sọrọ rẹ̀; ṣugbọn boya ki ire ije naa to pari a le dán igbagbọ́ wa wò ni ọna bẹẹ. Ohun kan ni a mọ̀ daju pe agbara eṣu ti n gbilẹ ni ayé yii n sun mọ ẹnu-ilẹkun wa si i lojoojumọ. Ohun ti o yẹ ki a ni lode oni ni lati jẹ́ alagbara ninu igbagbọ́ kan naa ti o sọ awọn eniyan mimọ́ igba ni di alagbara; Ọlọrun a si maa gbin igbagbọ́ yii sinu ọkàn ẹni ti o ba gbẹkẹ rẹ̀ le Ọlọrun.

**"Ṣugbọn nisisiyi nwọn nfẹ ilu kan ti o dara jù bẹ̃ lọ. . . ."**

Ohun kan tun wà sibẹ ti o sàn ju Ilẹ Ileri ni lọ pẹlu gbogbo wara ati oyin rẹ̀, pẹlu eso ajara Eṣkolu, ati gbogbo ibukun ti a le ri nibẹ.

**“. . . . . eyini ni ti ọ̀run: nitorina oju wọn kò ti Ọlọrun, pe ki a mã pe On ni Ọlọrun wọn; nitoriti o ti pèse ilu kan silẹ fun wọn” (Heberu 11:16).**

Bi O ba pese rẹ̀ silẹ fun wọn, O pese rẹ̀ silẹ fun awa naa.

Akoko kan de ti Abrahamu ri iyiriwo ti o ga ju lọ ni aye rẹ̀. Bẹẹ ni olukuluku wa yoo de ibi kan o pẹ́ o yá ni, ti ọran naa yoo wá si iwaju wa gbangba lati bá Ọlọrun là á já, ohunkohun iyowu ti o le gbà wá. Njẹ a o ha le la a já bi yoo ba gba pe ki a bẹ́ wa ni ori? tabi a o ha sá pada ni irú ipò bẹẹ?

Abrahamu dé ipò yii. Lati oju sanma ti o mọ́ gaara (lẹyin ti o ti duro fun ọdun mẹẹdọgbọn fun imuṣẹ ileri Ọlọrun pe lati inu iru-ọmọ rẹ̀ ni a o ti bukun fun gbogbo idile ayé) ni Ọlọrun ti sọrọ: “Abrahamu.” O si dahùn pe, “Emi niyi” Ọlọrun wi pe, “Mu ọmọ rẹ nisisiyi, Isaaki, ọmọ rẹ na kanṣoṣo, ti iwọ fẹ́, ki iwọ ki o si lọ si ilẹ Moria; ki o si fi i rubọ sisun nibẹ̀ lori ọkan ninu oke ti emi o sọ fun ọ” (Gẹnẹsisi 22:1, 2). Aṣẹ naa ni eyi. Ki ni Abrahamu ṣe? O dide ni kutukutu owurọ ọjọ keji, o si di kẹtẹkẹtẹ rẹ̀ ni gaari, o si la igi, o mu ọmọ rẹ̀ ati awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀, wọn si bẹrẹ si i lọ ni irin ọjọ mẹta si Moria. Nibẹ ni o ti ṣe gẹgẹ bi eyi ti Ọlọrun wi fun un.

**“Isaaki si sọ fun Abrahamu baba rẹ̀, o si wipe, Baba mi: on si wipe, Emi niyi, ọmọ mi. On si wipe, Wò iná on igi; ṣugbọn nibo li ọdọ-agutan fun ẹbọ sisun na gbé wà? “Abrahamu si wipe, Ọmọ mi, Ọlọrun tikalarẹ̀ ni yio pèse ọdọ-agutan fun ẹbọ sisun” (Genẹsisi 22:7, 8).**

Asọtẹlẹ nla ni a sọ ninu ọrọ wọnni nitori Abrahamu sọ gẹgẹ bi apẹẹrẹ ni lilọ si oke Moria, ohun ti yoo ṣẹlẹ ni ọgọrun ọdun pupọ lẹyin naa nipasẹ iru-ọmọ ti yoo jẹ́ ibukun fun gbogbo idile ayé. O mu Isaaki o si de e, o gbé e le ori pẹpẹ o si gbé ọbẹ soke. Nigba naa ni Ọrọ Oluwa tọ ọ wa pe, “Máṣe fọwọkàn ọmọde ni, bẽni iwọ kò gbọdọ ṣe e ni nkan: nitori nisisiyi emi mọ̀ pe iwọ bẹ̀ru Ọlọrun, nigbati iwọ kò ti dù mi li ọmọ rẹ, ọmọ rẹ na kanṣoṣo” (Gẹnẹsisi 22:12).

Oun ko jẹ ki ohun ti o ṣọwọn ju lọ fun ọkàn rẹ̀ leke ifẹ ti o ni si Ọlọrun. Bi oun kò ba ti fi Isaaki si ori pẹpẹ lati ibẹrẹ wá, ki bá ti ṣe e ṣe fun un lati tẹ ẹ sori pẹpẹ nigba ti iyiriwo nlá nlà yii de ba a. Bi o ṣe ti Abrahamu ni, o ti pa ọmọ naa. O ni igbẹkẹle pe oun n sin Ọlọrun kan ti o jẹ pe, bi oun ba mu aṣẹ Ọlọrun yii ṣẹ O lagbara lati ji ọmọ yii dide kuro ninu oku.

**“O si pari rẹ̀ si pe Ọlọrun tilẹ le gbe e dide, ani kuro ninu oku, ati ibiti o ti gbà a pada pẹlu ni apẹrẹ” (Heberu 11:19).**

Ọlọrun tipasẹ iṣe ọmọ eniyan fun wa ni apẹẹrẹ kekere nipa imuṣẹ ohun kan ti o ṣẹlẹ ni Ọrun nigba ti “Ọlọrun fẹ araiye tọbẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni.” Itumọ ọrọ ni “funni” ni pe O jọwọ Ọmọ bibi Rẹ̀ kan ṣoṣo.

**“Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun” (Johannu 3:16).**